# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AYE. TẸNI GBOGBO LAWA

No 774 WEDNESDAY AUGUST 19, 1964 (2D)


## Ọmọ Ile-Ekọ Kan Binu Pa Ara Rẹ

IBADAN ;– Ni Ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinogun oṣu yi ni ọ m ọ ẹkọ giga kan ni ile ẹkọ ti Kings College Eko Ọmọ ile ẹkọ na ni Adeniji Babalọla ẹni Ogun Ọdun binu pa ara rẹ pẹlu Ogun Oloro buburu kan ti a npe ni (Gamaline 20) eyiti ogbe fun ara rẹ jẹ.

Ọmọ ile ẹkọ giga na wa ninu Isimi eyiti o lọ ba ẹgbọn re ti ojẹ ọkan ninu awọn Olukọ ni ile ẹkọ giga ti Unifasiti ti Ifẹ ni Ibadan lati lọ lo Isimi rẹ pẹlu rẹ.

Gẹgẹbi ọrọ ti ẹgbọn ọdọmọkunrin na ọgbẹni Babalọla fi ye oniwe Irohin ni pe, nigbati on wo titi ti on ko ri ni on ba fi agbara si ilẹkun ibi ti Adeniji sun si. Ọgbẹni Babalọla tun ṣe alaye pe igbati on ṣi ilẹkun na oni on titi ba a ti oku ti o si ti di okuta sori ibusun rẹ ati pe on ba agolo mẹta ogun oloro buburu "Gamaline 20" lori tabili ni ẹba ibusun rẹ ti o ti gbe ogun na mu.

Oniwe Irohin fi ye wa pe nwọn ti gbe oku ọmọ kunrin na lọ si ile iwosan lakulaku ni Adeoye Ibadan fun ayẹwo oku ọmọ ile ẹkọ na.

# IYAAFIN AWOLỌWỌ GBAYI O GB'ẸYẸ!!

## Awọn Enia Ilesha Fi Iro Ibọn Ki Ku Abọ !!!

IBADAN:— Ọjọ nla ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi fun Oloye iyaafin H. I D Awolọwọ papa julọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ jakejado Ipinlẹ Iwọ Orun ilẹ Naijiria nigbati Iyaafin Oloye H, I. D, Awolọwọ Iyawo Olori ẹgbẹ Afẹnifẹni nigbati o dede lati Oke Ado Ibadan lati bere irin ajo rẹ si Gbọngan, Effon Alaye ni ẹkun Ondo, Apomọ Ile Ifẹ ati Oshun si ilu Ilesha ti gbogbo enia si bẹrẹ si kegbe Awo! Awo!! Awo!!



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ ATI IYAWO RẸ

Ko si ẹgbẹ oṣelu kan lati igba rogbodiyan ti ṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni nkan bi ọdun meji sehin ti o gba iyi ti Oloye Iya afin ati awọn Amẹwa rẹ gba laseko tabi ki Olori ẹgbẹ oṣelu kan rin iru irin ajo ti Oloye Iya afin Awolọwọ rin lai ko si mọto awọn Ọlọpa ki nwọn ki wọku inu rẹ lati le wa fun abo eyi to jẹ pe iya afin Oloye Awolọwọ si nlọ pẹlu Ọla nla rẹ lai ko si Ifoya kankan rara.

Ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni ọjọ kini fun irin ajo Oloye Iyaafin H. I. D. Awolọwọ kakiri agbegbe Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati le ba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ sọrọ lori eto awọn ohun to nṣẹlẹ lori ọrọ oṣelu ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Nigbati Oloye Iyaafin Awolọwọ lọ si Ilesha ibusọ marun si ilu Ilesha ni awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ ti nwọn wa ni ajumọṣepọ ti duro si oju ọna lati wa pade Oloye Iyaafin Awolọwọ pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ lati fun wọn ni ẹyẹ ku abọ pẹlu iro ibọn.

Oniwe irohin wa fi ye wa pe nigbati o ku nkan bi wakati kan ki Iya afin Oloye Awolọwọ yio de si ilu Gbọngan ni awọn igbimọ Afunishọ ti Ijọba ibilẹ ẹgbẹ Dẹmọ ṣe ofin pajawiri kan pe nwọn ko gbọdọ lu ilu kankan ni agbegbe ilu Gbọngan.

Oniwe irohin wa fi ye wa ninu irohin rẹ pe awọn onilu ti to lẹsẹsẹ si oju ọna lati fi ilu pade iya afin Awolọwọ ku abọ si ilu Gbọngan.

Ninu ọrọ ti iya afin Oloye Awolọwọ sọ fun awọn enia ilu Gbọngan ninu ọrọ rẹ Iya afin oloye Awolọwọ sọ pe ko si nkan to le ja ajumọṣepọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ati Alakukọ ka rara.

Iya afin Oloye Awolọwọ tun duro diẹ ni Oshun lati ki awọn enia to wa loju ọna lati ki ku abọ, awọn enia na si gbe patako kan lọwọ lokokan lati fi ki Iya afin Oloye Awolọwọ ki ku abọ ninu awọn patako ti nwọn gbe lọwọ na ni nwọn kọ (Zikist welcome Mrs Awolọwọ and welcome N, C,-N C. - A, G. (Alliance)

Awọn ọmọ ile ẹkọ awọn ẹgbẹ oṣelu lati Oshogbo Ilesha ati awọn agbegbe rẹ lo wa si Oshun pẹlu mọto ayọkẹlẹ nlanla lati wa pade iya afin Oloye Awolọwọ

Irohin tun fi ye wa pe nigbati iya afin Awolọwọ ati awọn ẹlẹgbẹrẹ de Ile-Ife pe nṣe ni ile ẹjọ to jẹ pe awọn Agbejoro (Lawyer) wa si sare jade lati wa ki iya afin Awolọwọ ku a bọ eyiti

Wo oju ewe kẹfa

## E San Ekunwo Owo-Oṣu Fun Awọn Oṣiṣẹ —Benson

EKO:— Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni Alakoso eto irohin fun Apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati igbakẹta Olori ẹgbẹ Alakukọ Oloye T. O. S. Benson rọ gbogbo awọn Alakoso ile iṣẹ ti ki iṣẹ ti Ijọba ilẹ Naijiria ati pe ti ko ti san ẹkunwo owo oṣu eyiti Igbimọ oluwadi Morgan ṣe lati tete san ẹkunwo owo na bayi.

Oloye T O S. Benson sọ ninu ọrọ rẹ pe oni lati han gbangba si oju gbogbo enia lati ri daju pe ko si ọrọ irọ lori adehun ti awọn aṣoju awọn oṣiṣẹ, ati awọn aṣoju fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati awọn aṣoju fun awọn Alakoso ile iṣẹ ti ki iṣẹ ti Ijọba ṣe lori adehun ti oloye Okotie- Eboh ṣe alaga rẹ Oloye Benson si tun sọ siwaju si i pe gbogbo enia lo mọ pe awọn Alakoso ile iṣẹ na si faramọ eto adehun na ki nwọn to gba lati le fi owo si adehun na.

Oloye Benson sọ ni ipari ọrọ rẹ pe o jẹ ohun to tọ ati eyi to yẹ lati le fun awọn Alakoso

WO OJU EWE KẸFA

# IWE SI OLOTU

## E Fun Awolọwọ Ni Ominira

Mba ṣọpẹ bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye ninu iwe irohin rẹ oloyin momọ lati bẹ Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria Alhaji Abubakar Tafawa Balewa ati Dokita Nnamdi Azikiwe, Olori Apapọ Ijọba Naijiria ki nwon jọwọ ki nwon fun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ni Ominira ki nwon da silẹ ni alafia ninu ọgba ẹwon,

Lati nkan bi Ọdun meji sehin ni Awolọwọ ti wa n nu isoro eyiti o jẹ pe lasiko yi kanna ni ofo kan tun sẹ sugbọn gẹgẹbi onigbagbọ ododo ogba gbogbo adanwo ti ode



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

Ṣugbọn nisisiyi ti otun ni ireti pe boya ominira yio wa fun on nipa ẹjọ kotẹmilọrun to pe oyẹ' osi tọ ki Alakoso wa' jọwọ ki o sanu Awolọwọ ki osi da silẹ ninu ọgba ẹwọn nitori laikosi Awolọwọ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun ko le toro

Mo bẹ Abubakar iati lo ipo rẹ rere yi ati da Oloye Awolọwọ silẹ ọgba ẹwọn

Ẹmi ni
Latifu Babalọla

EKO

## Imagbọn nfẹ-Erọ Asọrọma gbesi

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe nyin oloyinmọmọ lati kesi Alakoso eto irohin ti Ijọba ipinle Iwọ Orun Naijiria lati fun ilu Imagbọn ni ero asoromagbesi (Radio) Eleyi jẹ ohun iyalẹnu lati ri pe ọpọlọpọ awọn ilu keke ni agegbe Ijẹbu [o ni ẹrọ na ni ilu wọn, Iiu Imagan ko kere rara ati pe a ko mọ ohun to le fa ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ko fun ilu na ni anfani lati le ma gbọ awọn Irohin jake jado ilẹ Naijiria.

Mo si mọ pe to ba jẹ oni yi ni Ijọba ṣe tan lati fun ilu na ni ẹro asọrọmagbesi na oda miloju peko si ilu kankan ti ko ni gba apoti ẹrọ na si ile rẹ

Ohun to tun jẹ pataki ti ilu na Ifẹ ni ina Elentiriki eyiti

ojẹ pe okoja ni Ilu na ti awọn Ijọba ko fun ilu Imagbọn ni anfani lati le ma ri ina na tan

Awa ara ilu Imagbọn nile ati ni idalẹ ti ṣetan lati ni ina Elentiriki na ni ile wa ni ilu Imagbọn nitori abuku ni ina ta fun ilu Imagbọn

Mo dupẹ pupọ Olotu
Emi ni
Oye Ogunsanya

EKO

## E Jẹ Ki A Ni Itiju

Olotu, jọwọ fun mi ni aye ranpẹ ninu iwe yin Oloyinmọmọ lati gba Ijọba Ipinle Iwọ Orun ni iyanju diẹ lori ipo ti Ipinlẹ na wa loni yi.

Ojẹ ohu aini itoju lati ma a gbọ nipa iwa ti Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun nhu si awọn Ọba ati Ijoye Ipinlẹ na lori owo oṣu wọn

Lati nkan bi oṣu meje sẹhin ni ati ngbọ wipe owo awọn Ọba kan di kọbọ ni ọdun kan. ọrọ yi pami lẹrin pupọ, Njẹ ẹti gbọ iru ereyi ni ipinlẹ kankan ni ilẹ Naijiria wa ri? Tabi ẹ gbọ ri nigbati Ẹgbẹ Afẹnifẹre nṣe Ijọba Ipinlẹ na?

Ẹ jọwọ ẹmaṣe jẹki ama a fi Ipinlẹ wa ṣe yẹyẹ larin awọn ipinlẹ yoku ẹ jẹki a ma a ni itiju diẹ diẹ o



Oloye S. L. Akintọla

Mo bẹ Ọba ti ọwọ nyin ko ti di kọbọ ni oṣu lati fi ara mọ Ijọba ki ẹ nisuru fun igba diẹ ibo didi fẹrẹ de ki ẹ bọ kuro lọwọ ijọba alagbara

Emi ni
S Fẹmiyẹsin
Musnin


## EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE EGBOGI



"CYCLOVEN"

Aworan ẹgbẹyi fihan gban gba ibiti Jẹdijẹdi rẹ ba wa ara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma be ṣe igbọnṣẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun ọkunrin ti o si lagbara pupọ lai ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode ẹnisisiyi ti nwọn ma a polowo wọn un iwosan rẹ ṣugbọn boya la le ri mẹwa ninu awọn ogun ni o le ṣe iwosan aru yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile iwosan lati lọ ke eyiti oba nyọ jade lati omusu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa, Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọsẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijako ni ọjukanna pupọ ojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ fẹran Ṣuga oniruru ohun adidun pupọ, pupoju nigba kugba Jẹdijẹdi di orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omuṣu tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuṣu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ kio si danwo risi i mẹ a daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia lo de ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata nigboro Naijiria bere ni :

NIGERIAN MEDICENE STORES
Tinubu Square Lago
4, Adedun Chemist
14, Workeman Street, Yaba



# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING
*Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Becuase Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs —*
Just Call 21985 – Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Prnting Press**

**16 Bamgbose Stree**
Phone 21985, Lagos

# Ẹgbẹ Dẹmọ Ngba Awọn Digbolugi Ẹnia Sinu Ọlọpa Ibilẹ Iwọ Orun

Lati Ọwọ:- ỌLANIPẸKUN OKI,
Akọwe Ikede Ẹgbẹ Alakukọ Fun Iwọ Orun.

Irohin de ibi ile iṣẹ Ẹgbẹ Alakukọ ni ọsẹ to kọja wipe awọn Olori Ẹgbẹ Dẹmọ kan ngba awọn Digbolugi enia lati ilu Badagry lati ko wọn sinu awọn Ọlọpa Ibilẹ ti Iwọ Orun.

A tun gbọ siwaju si wipe awọn Digbolugi adamọdi Ọlọpẹ nwọn yi ni awọn Ẹgbẹ Dẹmọ fẹ lọ fun iṣẹ buburu pataki kan lasiko idibo to nbọ yi kakiri ipinle Iwọ Orun, Irohin na fi ye wa papa wipe nwọn ti nlọ kọ awọn Digbolugi enia nwọnyi nise gbogbo ti awọn Ọga won fẹ fun wọn ṣe na ni Ilu Franse French ni Potonovo bayi.

Nisisiyi Ọgbẹni Ọlanipẹkun Oki ti fi ọrọ na siwaju Ọga Ọlọpa Eko fun ayewo, torípe ti Ọlọrun ba ti fi ọta ẹni hanni kole pani mọ, bayi iru awọn Digbolugi enia ti nwọn ngbe nwọnyi dabi enia ẹni wipe ọna ati mu eto idibo daru tabi ki o ma lọ ni ọna ti ko o rọgbọ ni ọ fẹ jasi.

Bi o si ti jẹ wipe gbogbo ọna eru ni gbogbo ni Ẹgbẹ Dẹmọ yi sa nfẹ lo lati joko pa sori Ijọba, gbogbo nkan nfẹ itọsẹ ati akiyesi fin-ni-fin-ni.

Ṣugbọn bi Oluwa ti wa loke ati bi o ti ṣe jẹpe ọna jamba ati eru na ni Ijọba yi fi bẹrẹ asiri wọn yio ma tu si araiye lọwọ na ni titi asiko idibo yio fi de ti okunkun yio parada ti Imọlẹ o si wọle si Iwọ Orun Naijiria lati ọwọ ajọsepo Ijọba Ẹgbẹ Alakukọ ati Ẹgbẹ Ọlọrẹ. Ẹyin enia Ipinlẹ Iwọ Orun abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọ Luwabi ti o ba denu rẹ yio di odindi gbogbo irohin ti a ba tnu ngbọ a o ni ṣe alaima sun si oyin leti o.

# YE IRAWỌ RE WO

AGUARIUS (Jan 22–Feb 20) Ẹbun tabi ọrẹ ni iwọ yio jigba ni owurọ yi, ṣngbọn maṣe damu ọkan ara rẹ nipa rẹ.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Ẹnikan ti iwọ yio ba sọrọ pọ loni, ọrọ rẹ yio ṣe ọ ni anfani, ṣe suru, ki o si mu ọkan rẹ girigiri, bi ọ ba fẹ ṣe ohun kan. Asalẹ oni yio dara fun ọ.

ARIES Mar (21-April 20) Ayọ yio kun inu ọkan rẹ lalẹ oni, Ire airotẹlẹ kan yio yọ si ọ, gba mọra, ṣugbọn bi oba jẹ pe nṣe ni oni lati rin irinajo ki o sọra nitori janba mọto lọna. Ma ṣe ṣiṣẹ pupọ

TAURUS (April 21 – May 20) Jẹki eri wo ibi rere gbe ọ de, maṣe fi ọwọ ara rẹ fa nkan to wu ọ, eyiti o ba yọ si ọ lọwọ ni ki o gba, ki ijọngbọn kekeke ma ba soju rẹ delẹ, ati ki amodi ma ba ṣe ọ.

GEMINI (May 21 – June 21) Ọrọ ija kan larin ẹbi rẹ ni ki o jẹki o pari li asan yi, maṣe jade lọ sibi kan la lẹ oni, beni ki o maṣe rin lọ si ibikan ni ọla pelu

CANCER (June 22 – July 23) Ṣọra rẹ ni alẹ oni ki jamba kan ma ba ṣẹlẹ si ọ, ọkan rẹ yio nitẹlọrun, ifẹran ti o fẹran gbogbo enia yio ṣe ọ ni anfani.

LEO (July 24 – Aug 22) Ohun kan ninu dukia rẹ, yio marin gere bi o ba tọju rẹ, idunu ati ayọ ni igbẹhin rẹ yio jẹ fun ọ, iwọ o si le ṣiṣẹ aṣegbadun

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) Bi o ba le mu ileri rẹ ṣẹ, idunnu ati ayọ ni iwọ yio ba pade nibẹ. Ṣugbọn maṣe ba ẹnikẹni fi owo ṣire, akoko owurọ le sunwọn. ṣugbọn ọrọ ko ni dun ni aṣalẹ.

LIBRA (Sept 24 – Oct 23) Tete fi eri lele ki o sun lati oni, fi ọkan balẹ si ọgbọn ori rẹ, ṣugbọn ki o ma a wo iwaju ki o to fọ, ki o si toju alafia a a rẹ.

SCORPIO Oct 24 Nov 22:- Arẹ diẹ le ba ọ ja fun iba aye diẹ ti oni odara fun ọ ki o lọ sinmi, boya Ọlọrun le jẹki ori orun sun ki ara re sile

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Ijọgbọn mbọ loju alafia ara rẹ, Ronu jinlẹ nipa gbogbo nkan nisise bẹ ọwọ re yio tẹ ohun kan tio ti nlepa

CAPRICORN (Dec 22-Jan 21) Ṣọra ṣe bi iwọ ba kọ pe iwọ ko se ere mọ iwọ yio kọlu ijọgbọn nla kan mase sisẹ pakanleke nitori pe ara rẹ nfẹ itọju ijọgbọn ki o ma ba dina fun ọ.

# IKEDE
## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Eyi ni lati kede fun gbogbo ọmọ Ẹgbẹ Imọle Aiye Ọkunrin ati Obinrin wipe Calender ti ọdun 1965, eyi ti o jẹ ti ẹgbẹ yio jade laipẹ yi.

Ohun pataki ti o se idaduro fun un ni aworan gbogbo gboo (Ọmọ Ẹgbẹ) ti yio han ninu Calender na ninu ipade ti o kọja ni aya foto ti wa lati ya gbogbo wa, sugbọn ọpọlọpọ ti ko wa ni ọjọ na ko jẹ ki a le ya fọto na.

Nitori idi eyi ti o ba di ọjọ Sunday ni 23/8/64 a o ya fọto na lagbara Oluwa ni nkan bi agogo mẹta ọsan ni a o ya e. Ọmọ ẹgbẹ ti ko ba wa tabiti o ba pe lẹhin, ko ni han ninu aworan na a ko si ni ya foto na ni ẹmeji. Nitori idi eyi ki o tete de ipade ni ogogo meji (ni 16, Bamigbose St. Lagos.) nitoripe awọn atunse diẹ wa ki a to ya fọto.

"IJAFARA LEWU O"

RAHMAN DUMOYE
Alaga Ẹgbẹ Imọle Aiye.

# Awọn Ọja Ajẹbidan

Iwe ilana Ifa Iyanrin titẹ. Etutu ṣiṣe Iwosan ati egbogi ajẹbidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku koni yọọ lẹnu mọ oso ati ajẹ ko ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ni ohunkohun toba si dawọ rẹle ni yio ja ṣi rere awọn baba awon ti o gbowo gba asọ lọwọ enia ko ni ri gba mọ Iye owo rẹ 20/-

Iwe egbogi ajẹbidan Agbabiẹtu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wa ninu iwe yi ko ṣe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe yi lọwọ ṣaṣa arun ni o ko ni le wo ko si ni ijaiya pe arun tabi Amodi kan le pa ọ Iye owo 25/–

Turari Ẹyọ u Ajẹ- ti o ba nfin turari yi ba a ti ṣe sore rẹ Ajẹ ati abatenijẹ ko ni foju si ọ lara ohun kohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwọ kọ ni mọ aita ọja agbana ko si ni wọ igba rẹ idabobo siwa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| Pangolo kan | 10/6d |
| Kekere | 2/6d |
| Iwe Gbedegbẹyọ Hausa | 3/ |
| Itumọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Eewo ilẹ Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 3/6 |
| ati agbara Psalm ẹgun lori awọn Ajẹ pẹlu Ara | 30/- |
| Tailos Measurement works | 2/- 6d |
| Iwe lori iyege Ikọṣẹ (Certificate of Apprenticeship) | 5/– |
| ẹyọ kan | 12/- 6d mẹta |
| Iwe Adehun larin Onile ati mehaya Tenantş (Agr. ment Form) | 10/- 6d meji |
| Iwe Aṣofofo Alejo (Visitors not Book) | 2/-6d |
| Iwe Alagbafọ (Laundry Book) | 5/-6d |
| Kadi ifisọrọ sinu redio lọfẹ | 2d |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan fun itaja ati Iṣẹgun Ajẹ | 16/- |

## APEJUWE ILE IṢE WA

Wọ Bọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere bi, ti o ba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilo Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ti ile itawe wa wa. Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja rira adirẹsi mi niyi:—

J. O. Shoyinka
c/o Postal Agent,
1, Isiba Street
Itirẹ Via,

Lati Oju Ewe Keji

Ikọ Ọlọrun Fi Ibere Yi Siwaju Wọn Ẹni akọkọ ti o kọkọ bọ siwaju rẹ oduro ṣege, Ikọ Ọlọrun ni:- Ikọ Ọlọrun :- Iwọ Ọkunrin yi loni ni ọjọ pe ti iwọ nlọ si ile aiye mọ daju pe ọja ni ile aiye, Ọpọlọpọ na ọja tirẹ, o pada sile lowurọ kutukutu, omiran na tirẹ lọsan gangan opada sile ọjọ alẹ ni omiran to pada sile, mo ṣi fẹ ki ẹ mọ daju pe, erupẹ ni afi da nyin dajudaju eo si pada di erupẹ, ohunkohun ti ẹba si ṣe ni ile aiye nyin ni ao si da nyin lejọ, lọjọ ikẹhin Wi fun mi yi kini o fẹ da nile aiye rẹ? Ọkunrin:- Ohun ti mo fẹ da nile aiye mi ni pe ki nlowo jaburata, ki i ma fẹlẹlẹ ninu mọto, ki Obinrin yọtọmiyọtọmi wa ni agbole mi ki nsi ma fi igbadun ṣayọ. Ikọ Ọlọrun:- Bọ si apa kan na ni kukuru ako le ma pe nyin ni lọkaukan, tani ninu nyin ti onfẹ ira ohun ti Ọkunrin yi bere Ida mẹta ninu idamẹrin li o fara mọ Ọkunrin na, oni ki wọn papọ si ọdọ rẹ wọn si ṣe bẹ.

Ikọ Ọlọrun:- Ẹnyin to ku ẹronu jinlẹ ki ẹto yan ayanmọ nyin, kini ẹfẹ da ni ile aiye nyin Ọkunrin:- Ọkunrin kan jade, oni emi nitemi o, nko wa owo jaburata, ṣugbọn mo nwa owo niwọnbati ngo fi ma gbadun aiye, mo fẹ ọmọ, mo si fẹ ọgbọn ati oye lati ma tan ihin rere Oluwa ka ile aiye

Ikọ Ọlọrun:- Tanni ofara mọ ohun ti Ọkunrin yiwi? Ggbogbo wọn so pe afaramọ, o ni ki wọn papọ sọkan, wọn ṣe bẹ.

Nigbati olukuluku yan ohun ti o fẹ tan ikọ Ọlọrun bi wọn lere pe seẹ ti rodada ki ẹ to yan ipin cyin? wọn awọn ti yan o ni ẹnyin olufẹ ọwọn gbogbo nyin li ẹ ti yan ayanmọ yi adura mi si nipe ki o ri fun olukuluku gẹgẹbi ifẹ ọkan rẹ ẹbọ sihin ki ẹ wa fi gbongbo ika nyin sinu iwe agirimenti iwe adehun na lọ bayi pe Emi ọmọ enia tio nti kọle ọrun lo si ikọle aiye ṣe iwe adehun yi larin emi ẹlẹda pe ohun ti mo yan pe ngo ṣe ni ile aiye nko gbọdọ yi pada ti mo ba si gbadura si Ẹlẹda ki adura mi mase gba, mo si de adehun yi ni soju ikọ Ọlọrun mo si fi gbogbo ika mi tẹẹ loni yi.

Kia mọsa Olukuluku wọn ti bẹrẹsi fi ika tẹẹ nigbati wọn fi ika wọn tẹẹ tan ikọ Ọlọrun ni mo tun ran yin leti tiẹ lodi si ọrọ inu iwe yiti ẹ ba dele aiye, ẹ o jẹ ẹkọtọ iya ti ẹ b a pada de ajnle ọrun ohun kan li o ku ki ẹ to ma lọ ngo nyin de ọdọ Ẹlẹda Orun on aiye ẹtẹ le mi ka lo gbogbo w n si tẹle nigbati wọn de papa oko tutu minimini bi ọsan gbẹgẹ eti odo ẹiyẹ ko tilẹ ke rara. Ikọ Ọlọrun pasẹ fun wọn pe ki wọn kunlẹ wọn sj kunlẹ lọ rẹbẹtẹ o bẹrẹsi gbadura kikankikan ngibati oya imọlẹ kan la gboo kosi eda alaye tio le woo, omọlẹ ju crun lọ ohunkan si jade lati inu imọlẹ na ti o wipe:- Emi nj Ẹlẹda Ọrun on aiye tj ohun gbogbo ti nbẹ ninu wọn mo fi aṣẹ si pe ohun ti ẹ donjyan lọkan ki ori fun nyin bẹ ṣugbọn ohun ti ngo isọ fun nyin nipe ti ẹ ba de ile aiye ki ẹ fẹ ọmọnikeji nyin nitoripe eyi ni akoja ofin alafia ki o ma ba nyin gbe bi ohun yi ti dakẹ ni o unkun ṣu biribirl yiyọ ti wọn ma yọ iṣẹ ni wọn yo si arinagbede meji Ọrun on aiye.

# Jẹki Nrọọkan

Lati Oju Ewe Keji

ninu awọn ti mo darukọ yi! Bẹ si ni ọmọ rẹ bi iya wa awọn ti ngbọgọ obi ati ilu rẹ ga si wa pẹlu.

Mo ri iwe kan gba lati ilu oyinbo pe, awọn ọdọ wa nba oruko rere wa jẹ lọhun sẹ ẹnyin na mọ pe asesẹ soge ara oko bi kobale ọkan yio si din ọkan

Iwe na sọ pe ọkan ninu awọn ọmọbinrin wa fa ori rẹ kodoro, owa ra adamọ. dirun okd tapa India tin wọ pe ni igbo tẹlẹ rẹ bi ọlọgọ run pọun bi oti sọ ofurufu ni ilu Londonu ni awọn ọlọpa- nu tabi ọtẹlẹmuyẹ ti kiyesi irin re, nwọn fura si, nwọn pe ọlọpa obinrin ko lọ yẹ gbogbo ararẹ wo aṣe ẹru gọbọi wa ninu ori rẹ se ẹ ri nkan ti awọn ọmọ nyin nse?

N gbati ọwọ ntẹ awọn ọkunrin ni awọn obinrin na batun kosi owo iranu awọn ọmọ wa ti sọ wa ni su na ti nwọn kopa ẹran si Ọlọrun mo fun gb gbo wa ni ọmọ ti yio po wao ẹyara se amin rẹ witiwiti

Ẹnyin ti ẹni ki awọn ọmọ nyin mo lọ si ilu Oyinbo fun ẹkọ giga ọrọ rẹo rẹpẹtẹ ọran awọn ọmọ ti nba oru kọ rere ilẹ Naijiria jẹ nfẹ adura nla. Mo bẹ ẹnyin onigbagbọ ẹmọ ranti wọn ninu adura nyiu ati ẹyin onimọlẹ ẹ mọ gbagbe wọn ninu adura lẹhin pẹlu Fatia mẹwa mẹwa.


# Akiyesi

Si Gbogbo Ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ Abẹokuta ati agbegbe rẹ Ti o ba fẹ ra Irohin Imọlẹ ti o njade ni Ojọjumọ lọ ra lọwọ Aṣoju wa Omidan Owokọya.

*Owo Bookshop*
Shapon go - Oko Road
ABẸOKUTA

Ti Enikẹni ni Irohin Imọlẹ, kọbọ meji pere.



## OLUSHI SOCIALISTS

PRESENTS

FIRST ANNIVERSARY DANCE

**at Foresters Centenary Hall**
22, Odunlami Street Lagos

ON FRIDAY, 21st AUGUST, 1964, AT 6 p. m. till dawn

*MUSIC BY*

**New Time Enterprises**
**Bashy & His Young Stars Orchestra**

Ladies and Gents, dont be told of what happen at Foresters on that 21st August 1964, how Bashy will give you many latest hits and how New Time will give you many hits of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo & Broadway Dance Band Arom Ghana. Bashy is asuring you to bring along your Termogene or Mentholatum to rub your body after closing.

COME THERE IN TIME TO AVOID RUSHING

**Bar Bar Inexhaustible**
**Tickets 3s Flat**

Tickets obtainable at 16, Bamgbose Street Lagos (Irohin Imole Office) and at 3, Olushi Street Lagos



## PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti nyọ ẹ lẹnuto kan bi ọduo kan tabi ju ẹ lo awọn egbogi irọ i ni ese iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara, ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun In otutu, Ikọ ọna ofun, Ikọ Igbaaya, I ọ iil , Ikọ ti o mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba an lgo kan PORAL yi wa Iwọ na yio ri ayi tọ ninu ara rẹ ui kiakia Igbaaya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹundaradara iwọ yic si un fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orisiri i Lab gi Ikọ miran ni ọbu awọn:—

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos

Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji) .... ....
Adedun Chemist
14, Wa ... Street, Yaba

